# IGBEYAWO ỌDỌ-AGUTAN
## Ifihan 19:1-21
## ẸKỌ 464 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “O si ni lara aṣọ rẹ̀ ati ni itan rẹ̀ orukọ kan ti a kọ: ỌBA AWỌN ỌBA, ATI OLUWA AWỌN OLUWA” (Ifihan 19:16).**

### Orin Iyin Halleluya

Nigba ti Johannu Ayanfẹ wà ni Erekuṣù Patmo, nibi ti a le e lọ nitori o waasu nipa Jesu, o gbọ́, o si ri iran iyanu nla pupọ. Oluwa fi awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju hàn an.

Ninu ẹkọ yii, a kọ́ ẹkọ pe Johannu gbọ́ Orin Iyin Halleluyah ti ọpọlọpọ eniyan n kọ ni Ọrun, awọn ẹni Irapada Oluwa, eyi si ni orin ti wọn kọ: “Halleluiah; ti Oluwa Ọlọrun wa ni igbala, ati ọlá, ati agbara: nitori otitọ ati ododo ni idajọ rẹ̀.” Nigba ti ogun nla yii, lai si aniani, ọkẹ aimoye eniyan kọrin, o dún bi iro omi pupọ ati àrá nla: “Halleluiah: nitori Oluwa Ọlọrun wa, Olodumare, njọba. Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: nitoripe igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan.”

Nigbakuugba ninu isin ni ile isin, ni awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun n fi gbogbo agbara wọn kọ orin iyin si Ọlọrun; ṣugbọn awọn ẹgbẹ́ akọrin ọrun wọnyii yoo pọ̀ wọn yoo si logo ju ẹgbẹ́ akọrin ti a ti gbọ́ ri lọ.

O dabi ẹni pe a ká aṣọ iboju kuro, Johannu si ri ọjọ iwaju ti o jinna réré, nigba ti Jesu Kristi yoo dara pọ̀ mọ́ Iyawọ Rẹ̀, awọn aṣẹgun ti wọn ti wà ni imurasilẹ. A ka pe: “Ohun ti oju kò ri, ati ti etí kò gbọ, ti kò si wọ ọkàn enia lọ, ohun wọnni ti Ọlọrun ti pese silẹ fun awọn ti o fẹ ẹ” (1 Kọrinti 2:9). Ni ibi Ase Igbeyawo nla yii, Jesu tikara Rẹ̀ ni yoo ṣe iranṣẹ.

### Kù si Dẹ̀dẹ

A ti kọ iwe yii ni nnkan bi ẹgbẹwa ọdun sẹyin; ṣugbọn lonii, bi a ti n kọ́ ẹkọ Ọrọ Ọlọrun, a mọ̀ pe akoko kò ni pẹ́ mọ́, ṣugbọn “igba kù si dẹ̀dẹ” (Ifihan 1:3). Bi a ti mọ eyi, ẹ jẹ ki a kọ ori iwe yii pẹlu ero yii ni ọkàn wa pe awọn Ọrọ wọnyii wà fun anfaani wa; eyi ki i ṣe iran kan lasan ti Johannu ri, ṣugbọn ọrọ ti yoo mu wa yẹ ọkàn wa wò ni lati ri i daju pe a wà ni imurasilẹ.

### Iyawo Ọdọ-Agutan

Johannu kọwe pe a wọ Iyawo Ọdọ-Agutan ni aṣọ ọgbọ wiwẹ, ti o mọ́ ti o si funfun gboo, o si ṣe alaye pe eyi ni i ṣe “ododo awọn enia mimọ́,” eyi ti i ṣe apẹẹrẹ ọkàn aileeri, ti a sọ di mimọ́.

Ninu ẹkọ wa a ti kọ́ ẹkọ pupọ bi a ṣe le gbà wá là kuro ninu ẹ̀ṣẹ; ati lẹyin eyi, fifi ara wa rubọ lati wá isọdimimọ́ ati agbara Ẹmi Mimọ́. A ti kọ́ ẹkọ pe lai si iwa mimọ́, kò si ẹni ti yoo ri Oluwa, a ti kọ́ ẹkọ pe a ko le ṣe alai ni “ororo” àníkún tabi Ẹmi Ọlọrun, nitori eyi ṣe pataki ki atupa wa ba le maa jò titi Ọkọ Iyawo yoo fi dé.

### Ipadabọ̀ Jesu

Ipadabọ̀ Jesu pín si ọna meji tabi ipa meji: wiwá Rẹ̀ gẹgẹ bi ole ni oru lati pa Iyawo Rẹ̀ ti n ṣọna larada, Ounjẹ-Alẹ Ase Igbeyawo ti Ọdọ-Agutan yoo si tẹle eyi; lẹyin eyi, ipadabọ̀ Jesu ni igba Ifihàn, nigba ti gbogbo oju yoo ri I. Johannu ṣe apejuwe ipadabọ yii ninu Ifihan ori kọkandinlogun ẹsẹ̀ kọkanla titi dé ẹsẹ̀ kẹrindinlogun. Ẹ jẹ ki a fi oju ẹmi wo apejuwe yii. Ohun kin-in-ni ni pe o rí Ọrun ṣi silẹ, ẹṣin funfun kan si jade; ẹni ti o n gun ẹṣin yii ni Jesu Kristi, Ẹni ti oju Rẹ̀ dabi ọ̀wọ́ iná ati ni ori Rẹ̀ ni ade pupọ wà. A ti tẹ aṣọ Rẹ̀ bọ inu ẹjẹ, a si n pe orukọ Rẹ̀ ni “Ọrọ Ọlọrun.” O si ni orukọ lara aṣọ Rẹ̀ ati ni itan Rẹ̀ pẹlu, “ỌBA AWỌN ỌBA, ATI OLUWA AWỌN OLUWA.” A, irú iran wo ni o logo bayii!

Lati ẹnu Rẹ̀ ni idà mimú ti n jade lọ, ki o le maa fi ṣá tabi pa awọn orilẹ-ede; Oun o si maa fi ọpa irin ṣe akoso wọn. Pẹlu oju ti o dabi iná ati ida mimu, Oun le ri O si le pa gbogbo nnkan ti o lù mọ́ ẹ̀ṣẹ ti o si jẹ́ aimọ́ run.

### Awọn Eniyan Mimọ́ lori Ẹṣin Funfun

“Awọn ogun ti mbẹ li ọrun ti a wọ̀ li aṣọ ọ̀gbọ wíwẹ, funfun ati mimọ́, si ntọ ọ lẹhin lori ẹṣin funfun.” Awọn wọnyii ki i ṣe awọn miiran bi ko ṣe awọn eniyan mimọ́, Iyawo ti a ti darukọ rẹ̀ niṣaaju ninu ẹsẹ̀ keje. Ẹni ti ọkàn rẹ ko ba mọ́ ki o si funfun ki yoo ni ipin ninu eyi. Iyawo Rẹ̀ “si ti mura tan.” A mọ pe o gba Ẹjẹ

Jesu lati gbà wá là ati lati sọ wa di mimọ́, ṣugbọn siwaju si i nnkan kan wa fun wa lati ṣe. A gbọdọ gba agbara ifi Ẹmi Mimọ wọni pẹlu. Lẹyin naa, a gbọdọ maa ṣọna, ki a maa gbadura, ki a si maa ka Ọrọ Ọlọrun, a gbọdọ lo gbogbo anfaani ti a ni lati lọ si isin, lati jere ọkàn fun Jesu, lati fi ara wa rubọ ati lati jọwọ ayé wa fun Ọlọrun lojoojumọ. Ẹ máṣe jẹ ki a ká ọwọ́ gbe inu, ki a si wi pe, "A ti gba mi là; a ti sọ mi di mimọ; mo ti ni agbara Ẹmi Mimọ́; mo wà ni imurasilẹ fun bibọ̀ Jesu, ko si si ohun kan ti o kù fun mi lati ṣe."

**Aṣodisi-kristi**

A kà ninu Ẹkọ 462 nipa ẹranko naa, eyi ti a n pe ni Aṣodisi-kristi pẹlu. Johannu sọ nipa ẹranko yii pẹlu awọn ọba buburu ayé nigba ti wọn gbá ogun jọ lati bá Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa ati ogun Rẹ̀ jà. Ṣugbọn a mọ Ẹni ti o ṣẹ́ ogun naa -- Ọgagun igbala wa ni! A kà ninu 2 Tẹssalonika 2:8, pe Oluwa yoo pa "Ẹni ẹṣẹ nì … fi ẽmi ẹnu rẹ pa, ti yio si fi ifihan wíwa rẹ sọ di asan." O mu ẹranko naa ati wolii eke naa, O si sọ wọn laaye sinu adagun iná ti n fi sulfuru jó, ibi ti a n dá ni loro titi laelae, nitori a ki i pa iná naa, iná naa ko si ni jó eniyan ni ajo pa. Yoo maa joró titi, ki yoo si kú laelae.

**Idà**

Awọn ogun ẹranko naa ati wolii eke naa ni a fi idà ti o jade lati ẹnu Kristi ti o wà lori ẹṣin funfun pa. Ni igba pupọ ninu Ọrọ Ọlọrun, ni a n pe Bibeli ni "ida." Jesu wi pe, "Ọ̀rọ ti mo ti sọ, on na ni yio ṣe idajọ rẹ̀ ni igbẹhin ọjọ" (Johannu 12:48). Ninu Heberu 4:12 a kà pe, Ọrọ Ọlọrun "mú jù idak'ida oloju meji lọ" o si ni agbara paapaa lati wá ero ati ete ọkàn wa ri. Johannu wi pe lati ẹnu Jesu wa "ni ida oloju meji mimu ti jade." Ida yii n ṣe apẹẹrẹ Ọrọ Ọlọrun nipa eyi ti a o fi ṣe idajọ awọn eniyan. Pẹlu "ida" naa ni Jesu yoo fi "ṣá awọn orilẹ-ède."

**Ase-Alẹ ti Ọlọrun Alagbara**

Iran miiran ti o tun ya ni lẹnu ti Johannu ri ni angẹli ti o duro ninu oorun, ti o si kigbe lohun rara si awọn ẹyẹ ti n fò ni oju ọrun, "Ẹ wá, ẹ si kó ara nyin jọ pọ̀ si àse-alẹ nla Ọlọrun; ki ẹnyin ki o le jẹ ẹran-ara awọn ọba, ati ẹran-ara awọn olori ogun, ati ẹran-ara awọn enia alagbara, ati ẹran awọn ẹṣin, ati ti awọn ti o joko lori wọn, ati ẹran-ara enia gbogbo, ati ti omnira, ati ti ẹrú, ati ti ewe ati ti àgba." Iru ase nla wo ni eyi, nigba ti gbogbo awọn gunnugun, kannakanna, ẹyẹ àkọ̀, ẹyẹ alawọ rusurusu, aṣa, idi ati gbogbo oniruuru ẹyẹ lati gbogbo orilẹ ayé yoo kó ara wọn jọ si ibi kan lati jẹ ẹran-ara awọn eniyan buburu ti wọn bá Kristi jagun ti a si ṣẹgun wọn!

**"ỌBA AWỌN ỌBA ATI OLUWA AWỌN OLUWA"**

Ọba awọn ọba ti ni iṣẹgun lori agbara Eṣu! Njẹ o jẹ ohun iyalẹnu pe awọn agba nì wolẹ, wọn si foribalẹ fun Un? Njẹ o jẹ ohun iyalẹnu pe ogun nla nla nì ni Ọrun kọrin "Halleluiah" si Oluwa awọn oluwa? Ha, bawo ni yoo ti dara to bi gbogbo awọn eniyan nibi gbogbo ba le wolẹ niwaju Rẹ̀ nisisiyii, ki wọn si jọwọ ayé wọn fun Un, ki wọn si dara pọ̀ mọ́ awọn wọnni ti n sin Ọba nla yii.

Njẹ iwọ ti ṣe E ni Ọba igbesi-ayé rẹ bi? Njẹ iwọ n bu ọla fun Un ninu ohun gbogbo ti iwọ n ṣe ati ti iwọ n sọ bi? Njẹ ọmọ Ọba naa ni iwọ i ṣe?

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni orin ti awọn ọpọ akọrin ti n kọrin Halleluiah ni Ọrun n kọ?
3 Ki ni itumọ Igbeyawo Ọdọ-Agutan?
4 Bawo ni a ṣe wọ Iyawo laṣọ?
5 Apẹẹrẹ ki ni eyi jẹ́?
6 Ṣe apejuwe Ọba ti n gun ẹṣin funfun.
7 Ki ni aṣọ awọn wọnni ti wọn tẹle E lori ẹṣin funfun?
8 Ki ni ikede ti angẹli ti o duro ninu oorun ṣe?
9 Ta ni awọn ọba ayé ati awọn ogun wọn bá jagun?
10 Ki ni idà ti o jade lati ẹnu Jesu wá n ṣe apẹẹrẹ rẹ̀?
11 Awọn ikilọ wo ni o wà ninu ori iwe yii fun wa?